# KRISTI, ỌDỌ--AGUTAN ỌLỌRUN

**Isaiah 53:1-12; Iṣe Awọn Apọsteli 8:26-35**

**ẸKỌ 367 --- FUN AGBA**

**AKỌSORI: "A kẹgan rẹ̀ a si kọ̀ ọ lọdọ awọn enia, ẹni-ikãnu, ti o si mọ̀ ibanujẹ: o si dabi ẹnipe o mu ki a pa oju wa mọ kuro lara rẹ̀; a kẹgàn rẹ̀, awa kò si kà a si" (Isaiah 53:3).**

## I Awọn Asọtẹlẹ Nipa Kristi

1 Oluwa tọ awọn Ju wa, ṣugbọn aigbagbọ wọn fọ wọn loju, wọn kò si gba A gẹgẹ bi Messia wọn, Isaiah 53:1; Johannu 12:38; Romu 10:16

2 Iwa irẹlẹ ati iwa tutu Jesu kò jẹ ki ọ̀pọlọpọ eniyan ki o fà mọ Ọ, Isaiah 53:2; 52:14

3 A kẹgan Rẹ̀; a kò si ka A si, Isaiah 53:3; 50:6; Matteu 26:67; 27:30, 31

4 O jiya nitori awọn ẹ̀ṣẹ ti ki i ṣe ti Rẹ̀; a si kó aiṣedeedee wa le E lori, Isaiah 53:4-6; Matteu 8:17; 1 Kọrinti 15:3; Heberu 5:8; 1 Peteru 2:24

5 Pẹlu irẹlẹ ati itẹriba, O fi ara da ikú kikoro ati aitọ́, Isaiah 53:7, 8; Matteu 26:62, 63; 27:11, 12; Iṣe Awọn Apọsteli 8:32, 33

6 O kú pẹlu awọn eniyan buburu, a si sin In pẹlu ọlọrọ, Isaiah 53:9; Matteu 27:57-60

7 Nitori Ẹjẹ Etutu Rẹ̀, ikú Rẹ̀, ajinde Rẹ̀, ati ẹ̀bẹ Rẹ̀, Oun yoo ra idariji fun ọ̀pọ eniyan, yoo si bori gbogbo awọn ọta Rẹ̀ nikẹyin, Isaiah 53:10-12; Luku 22:37; Iṣe Awọn Apọsteli 13:38; Romu 3:25; 5:15, 18

8 Filippi mú ọrọ Isaiah 53:7, 8, o si waasu Jesu fun iwẹfa nì, Iṣe Awọn Apọsteli 8:26-35; Luku 24:27; Iṣe Awọn Apọsteli 18:28

## ALAYE

Isaiah ori kẹtalelaadọta jẹ ọkan ninu awọn ori iwe inu Bibeli ti awọn eniyan fẹran ju. Gbogbo eniyan ni o gbọdọ kọ́ ọ sori. Gbogbo awọn ọmọlẹyin Jesu ni o mọ̀ daju pe Jesu ni ori iwe yii n tọka si. Ori iwe yii ni Iwẹfa ara Etiopia n kà nigba ti Filippi pade rẹ̀. Filippi beere lọwọ rẹ pe, "Ohun ti iwọ nkà nì, o yé ọ?" Iwẹfa naa dahun pe, "Yio ha ṣe yé mi, bikoṣepe ẹnikan tọ́ mi si ọna?" "Filippi si yà ẹnu rẹ̀, o si bẹ̀rẹ lati ibi iwe mimọ́ yi, o si wasu Jesu fun u."

### Aigbagbọ́ Awọn Eniyan

Wolii naa ṣe apejuwe yekeyeke bi ijiya Olugbala ti ri gan an bi ẹni pe oun paapaa duro lẹsẹ agbelebu ti o n ri ohun ti o ṣẹlẹ.

Nigba ti o wo iwaju ti o si ri bi awọn Ju alaigbagbọ ti kọ Olugbala, o kigbe soke pe, "Tali o ti gbà ihin wa gbọ́?" Eredi meji ni o wà ti wọn fi ni lati gbagbọ́. Ekinni ni pe awọn wolii bẹrẹ lati ọdọ Mose ti sọtẹlẹ nipa bibọ̀ Olododo naa. Ṣugbọn idaamu wọn ni pe wọn n reti ẹni nla kan ti yoo fara hàn pẹlu ogo ati ọla ọba. Wọn kò le gbagbọ pe Oninu tutu ati Onirẹlẹ bi ara Nasarẹti nì le jẹ́ Olugbala wọn.

Eredi keji ti wọn fi ni lati gbagbọ́ ni oriṣiriṣi iṣẹ ami ati iṣẹ iyanu ti o tẹle iṣẹ-iranṣẹ Rẹ̀. A fi "apa OLUWA hàn" ni ṣiṣe awotan àrun ti kò ṣe e wosan. A ji awọn okú dide, a wẹ awọn adẹtẹ mọ́, a la oju awọn afọju, eti awọn aditi si gbọran. Kò si àrun ti kò fò lọ labẹ agbára nla Rẹ̀.

Jesu sọ fun awọn eniyan ni ọjọ kan pe: "Ẹ gbà mi gbọ́ pe, emi wà ninu Baba, Baba si wà ninu mi: bikoṣe bẽ, ẹ gbà mi gbọ́ nitori awọn iṣẹ na pãpã" (Johannu 14:11). Kò si ẹnikan ti o ti ṣe iṣẹ-iyanu ti O ṣe. Sibẹ ọkàn wọn kún fún aigbagbọ́.

Nigba ti a ba ro iye igba ti a ti fi apa Oluwa hàn ni akoko tiwa yii ninu Ihinrere Arọkuro Ojo bi Oluwa ti wo oniruuru àrun sàn, ti oriṣiriṣi iṣẹ-iyanu si ti n ṣe, o ya awa paapaa lẹnu bi awọn eniyan ti jẹ́ alaigbagbọ́. O dabi ẹni pe iboju ti o wà loju awọn Ju ni o tun bo awọn Keferi loju.

**Ibanujẹ ati Ẹdùn**

Ibanujẹ ati ẹdùn ti fi àpá si i lara to bẹẹ ti oju rẹ fi bajẹ ju ti ẹnikẹni lọ. Kò ni ẹwa ti yoo fi fa awọn eniyan wá si ọdọ Rẹ. Kò si ẹnikan ṣaaju Rẹ tabi lẹyin Rẹ ti O le ru ẹru ijiya ẹda ti O rù. Ninu Ọgba nì, O kigbe soke pe, "Ọkàn mi bajẹ gidigidi titi de ikú." O ru ẹru wuwo naa lọ ni ọna Rẹ si Kalfari. O kú ikú ibanujẹ. Awọn Ju ro pe ẹlẹtàn ni ati nitori eyi ni Ọlọrun ṣe lu U. Aigbagbọ́ fọ́ wọn ni ojú.

**Etutu**

Etutu ti Jesu ṣe lori oke Kalfari jẹ́ etutu pipe fun ara ati ọkàn. O ru ibanujẹ ati ikaanu wa lọ. Ibanujẹ yii n tọka si ti ọkàn ati inu -- awọn ẹ̀ṣẹ̀ wa. O rù wọ́n ni ara Rẹ lori agbelebu. Ẹni ti kò mọ ẹ̀ṣẹ, a fi ṣe ẹ̀ṣẹ fun wa, ki a ba le mu aiṣedeedee wa lọ.

Ninu ẹdùn ni ipọnju ti ara. O gbé awọ ẹda wọ̀ ki Oun ba le mọ awọn ailera wa. Ati nipa ìnà Rẹ ni a mú wa lara dá.

Iyọrisi ẹ̀ṣẹ ni aisàn. Lọna kan, tabi lọna miiran, bi o ba ṣe pe kò si ẹ̀ṣẹ lati igba ipilẹṣẹ ayé, aisàn ki bá ti si. Etutu Jesu tó fun mejeeji. Bi o tilẹ jẹ pe ẹbọ yii jẹ pipe ati alainiwọn ti o si tó lati gba olukuluku ẹni ti a ba bi tabi ti a o bi sinu ayé yii là, sibẹ ẹni ti o ba ronupiwada ẹ̀ṣẹ rẹ̀ ni o le jẹ anfaani Etutu naa. Ọlọrun n fi aanu lọ ni, ṣugbọn a ni lati kọ́ gba aanu yii ki a to le ri idariji gbà.

**Irọpo**

"Ina alafia wa wà lara rẹ̀." Awọn obi a maa na awọn ọmọ wọn ti o ṣaigbọran lati mú wọn wá si ipa ọna titọ́. A lu **U** nitori aiṣedeedee wa. Ẹni ti kò mọ ẹ̀ṣẹ, ti kò si ṣe aiṣedeedee ri, ni a lù lati ọdọ Ọlọrun wá nitori ẹ̀ṣẹ wa, ki a ba le ni alaafia pẹlu Ọlọrun. O di arọpo fun wa, ẹmi Rẹ fun ẹmi wa, ki igbesi-ayé wa le mú èso alaafia ati ododo jade.

**Idajọ Aiṣododo**

"Ni irẹsilẹ rẹ̀ a mu idajọ kuro." Wọn fi I pe ẹlẹtan, a kò si ṣe idajọ ododo fun Un. "Kan a mọ agbelebu, kan a mọ agbelebu" ni ogunlọgọ awọn onikupani naa n ké. A kò fun Un ni ẹlẹri kan lati jẹri si iwa rere Rẹ. O fara da a pẹlu ọkàn tutu ati irẹlẹ. Gẹgẹ bi ọdọ-agutan ti i yadi niwaju olurẹrun rẹ̀ Oun kò ya ẹnu Rẹ. Ọkan ninu awọn iwa rere Jesu ti o tayọ ni idakẹjẹ Rẹ. "Nigbati a si nkà si i lọrùn lati ọwọ́ awọn olori alufa, ati awọn àgbãgbà wá, on kò dá hùn kan. Nigbana ni Pilatu wi fun u pe, Iwọ ko gbọ́ ọ̀pọ ohun ti nwọn njẹri si ọ? On kò si dá a ni gbolohun kan; tobẽ ti ẹnu yà Bãlẹ gidigidi" (Matteu 27:12-14).

**Iboji Rẹ̀ pẹlu Awọn Ọlọrọ**

Nipa kikan Jesu mọ́ agbelebu pẹlu awon ole meji, ero wọn ni pe ki Oun ki O le ṣe iboji Rẹ pẹlu awọn eniyan buburu. Ohun ẹsin nla gba a ni pe ki a du ni ni isinku ọ̀wọ̀. Ọlọrọ kan ti a n pè ni Josẹfu ara Arimatea tọ Pilatu lọ lati bẹbẹ fun okú Jesu. Ọkunrin ọlọrọ miiran pẹlu ti a n pè ni Nikodemu, ijoye ninu sinagọgu, mú ohun ikunra oloorun didun wá awọn mejeeji si tẹ́ okú Jesu sinu iboji ti a kò ti i sin eniyan si ri. Bayii ni a mu asọtẹlẹ wolii Isaiah ṣẹ.

**Ọna Si Iye**

"Gbogbo wa ti ṣina kirikiri bi agutan." Awa ti ṣako kuro ninu agbo, ara ẹ̀ṣẹ wa ti ti wá gbọngbọn sinu iparun – a ti ṣegbe, ègbé ayeraye! Ṣugbọn Oluwa ti mu gbogbo aiṣedeedee wa pade ni ara Rẹ. Jesu ni ọ̀na pada si iye, ilẹkun ti o ṣi nipa eyi ti a le wọle ki a si yè. Agbelebu oró, ijiya kikoro, ṣugbọn O fara da gbogbo rẹ̀ lai si ikunsinu ki awa ba le ri ọ̀na pada si ọ̀dọ Ọlọrun. Awa kò tun duro leti bèbè egbe ayeraye mọ lati wo inu okunkun rẹ̀, ki a si wi pe, "Kò si ireti." Jesu ti dí ọgbun nla naa. O gbé wa ni apa Rẹ, O si mú wa pada sọdọ Ọlọrun (Luku 15:5).

**"A! ifẹ ti o mu eto igbala wá!**

**A! oore-ọfẹ ti o mu tọ eniyan wa!**

**A! ọgbun nla ti Ọlọrun dí**

**Ni Kalfari!**

**Nibẹ aanu tobi, oore si wa lọfẹ;**

**Idariji kun idariji fun mi nibẹ;**

**Nibẹ ni ọkan wuwo mi ri isinmi,**

**Ni Kalfari."**

A jẹ olododo niya bi ẹlẹbi, ki ẹlẹbi le ri ère gbà bi ẹni pe oun ni olododo.

### Irú Ọmọ Rẹ̀

"Yio ri iru-ọmọ rẹ̀, yio mu ọjọ rẹ̀ gùn, ifẹ Oluwa yio ṣẹ li ọwọ́ rẹ̀." Bi o tilẹ jẹ pe ati ke E kuro ni ilẹ alaaye, sibẹ iru-ọmọ Rẹ̀ -- awọn Onigbagbọ -- pọ pupọ. Ogunlọgọ ni o ti fọ aṣọ wọn ninu Ẹjẹ Ọdọ-agutan ti a si ti bi wọn sinu Ijọba Ọlọrun. Johannu ri ọpọlọpọ eniyan ti ẹnikẹni kò le kà lati inu orilẹ-ède gbogbo, ati ẹya, ati eniyan, ati ède gbogbo wá, wọn duro niwaju itẹ ati niwaju Ọdọ-agutan naa, a wọ wọn ni aṣọ funfun, imọ ọpẹ si wà ni ọwọ́ wọn. A ha ka ọ mọ́ ọ̀kan ninu awọn alaigbagbọ Ju bi? tabi a kọ orukọ rẹ silẹ ninu Iwe Iye Ọdọ-agutan.

### Oju Isọtẹlẹ

Nipa oju isọtẹlẹ, Isaiah wo iwaju o si ṣe apejuwe igbesi-ayé Kristi perepere (ṣugbọn ni kukuru) gẹgẹ bi ti Matteu, Marku, Luku ati Johannu, awọn ti o rin lẹgbẹkẹgbẹ pẹlu Rẹ̀ nigba ti Oun wà ni ayé nihin. O ri Jesu pẹlu oju isọtẹlẹ lati igba ewe Rẹ̀ titi di igba ti O ṣaanu fun ẹgbẹẹgbẹrun awọn eniyan ti O si wo awọn alaisan wọn sàn; ati lati ọjọ ìrẹsilẹ ati idajọ Rẹ̀ nigba ti O ṣe ikú Rẹ̀ pẹlu awọn eniyan buburu ati iboji Rẹ̀ pẹlu awọn ọlọ́rọ̀.

Wolii naa ri I pẹlu lẹyin ajinde Rẹ̀. O ri Ijọ ti a fi Ẹjẹ Ọdọ-agutan rà ati iṣẹgun Oluwa nikẹyin nigba ti yoo pin ikogun pẹlu awọn alagbara.

Irú igbesi-ayé wo ni yii! Irú Olugbala wo ni yii! Ọna Ihinrere Ọlọrun ti jẹ́ iyanu tó lati mú iran Adamu ti o ṣubu pada wá si ojurere pẹlu Ọlọrun!

### AWỌN IBEERE

1 Ta ni Wolii Isaiah n sọrọ nipa rẹ̀ ninu ori kẹtalelaadọta iwe rẹ̀?

2 Bi ẹ̀ṣẹ ba ti mu ibanujẹ wá sinu ọkàn wa, ki ni o mú bá agọ ara wa?

3 Ki ni ọrọ yii já si: "A mu u wá bi ọdọ-agutan fun pipa"?

4 Awọn ẹlẹri meloo lo jẹri si iwa rere Jesu nigba ti a n wadii ẹjọ Rẹ̀?

5 Ki ni Etutu nì tó fun?

6 Ta ni o sin Jesu?

7 Ta ni awọn irú-ọmọ Jesu?

8 Ki ni itumọ pinpin ikogun pẹlu awọn alagbara?

9 Ọna wo ni ikú Jesu fi jẹ́ irọpo fun wa?